**Fún Ìtumọ̀ èdè**
**Lancet Global Health**

**Abala Afoyemọ**


**Ọrọ Akọsọ** Lilo akojọ-fayẹwo iwakiri ti pato orilẹ-ede lati se apejuwe isẹ ajakale-arun ayọkẹlẹ le serànlọwọ fún awọn ipinnu nipa akoko fun abẹrẹ ajesara jak;alẹ-arun ayọkẹlẹ. A se atupale akojọ-fayẹwo iwakiri lati awọn orilẹ-ede Afirika lati se afihan akoko ti awọn ajakale-arun ayọkẹlẹ akoko lati se itọni fun awọn ilana abẹrẹ ajesara orilẹ-ede.

**Awọn ọna ise** A lo akojọ-fayẹwo sentinel ti o wa ni arọwọto awujọ lati awọn orilẹ-ede ti n se ijabọ si Global Influenza Surveillance and Response (GISRS) pẹlu awọn ọdun 3 si 10 ti akojọ-fayẹwo ti a gba l'akoko ọdun 2010 si 2019. A se isiro isikiri didara ọlọsẹ 3 ti ipin ti awọn ayẹwo ti o dara fun ọlọjẹ àjàkálẹ-arun ayọkẹlẹ ati iṣiro akoko ajakale-arun nipa lilo ọna apapọ iwọntunwọnsi. Awọn ibẹrẹ ati ipari ti ajakale-arun kọọkan ni a salaye gẹgẹbi ọsẹ àkọkọ nigbati ipin naa ba ti kọja tabi lọ si isalẹ aropin ọdọọdun, ni sisẹntẹle, fun ọsẹ ≥mẹta tabi ju bẹẹlọ to tẹlera. A pin awọn orilẹ-ede si awọn ọna ajakale-arun marun: Ẹya-Aye Àríwá (NH) ajakale-àrùn ti o waye ni Osu Kẹwa-Oṣu Kẹta, Ẹya-Aye Gusu (SH) ti o waye ni Oṣu Kẹrin-Oṣu Kẹsan, ni pataki Ẹya-Aye Àríwá pẹlu diẹ ninu isẹlẹ ajakale-arun ni awọn osu ẹya-aye gúsù, ni pataki ẹya-aye gúsù pẹlu diẹ ninu isẹ ajakale-arun ni awọn osu ẹya-aye àríwá, ati gbigbe arun ayọkẹlẹ ni gbogbo ọdun laisi akiyesi ẹya-aye àríwá tabi ẹya-aye gúsù ìjẹgàba (kosi apẹẹrẹ tó f'oju han).

**Awọn awari** Ninu awọn orilẹ-ede mẹrinlelọgbọn to njabọ akojọ-ọrọ si FluNet, mẹẹdọgbọn ní ó–keere-jù ọdun mẹta akojọ-ọrọ, eyiti o nsoju mẹrindinlaadọta ninu ọgọrun (46%) awọn orilẹ-ede ni Afirika ati mọkandinlaadọrun ninu ọgọrun (89%) awọn eniyan Afirika. Awọn orilẹ-ede fun iwadii ti jabọ esi wipe àwọn àbájáde kòkòrò-afàìsàn eemi ti RT-PCR fun apapọ apere 503,609 (ti agbedemeji jẹ 12971 [IQR 9607 – 20960] fun orilẹ-ede-ọdun) ninu eyiti 74001 (15%; agbedemeji 2078 [IQR 1087 – 3008] fun orilẹ-ede-ọdun) jẹ ohun rere fun awọn kòkòrò-afàìsànarun ayọkẹlẹ. Awọn ajakalẹarun 248 waye ni gbogbo akojọ-ọrọ ti 236 awọn ọdún orilẹ-ede (agbedemeji: 10; [gbedeke: 7-10] fun orilẹ-ede kookan). Awọn orilẹ-ede mẹfa (24%) ní ilana ẹya-aye àríwá (Algeria, Egypt, Tunisia, Burkina Faso, Niger, ati Morocco). Mẹjọ (32%) ní apẹrẹ ẹya-aye àríwá àkọkọ pẹlu diẹ ninu awọn ajakale-arun ẹya-aye gúsù (Cameroon, Ethiopia, Mali, Nigeria, Senegal, Togo, Tanzania, ati Mozambique). Mẹta (12%) ní apẹrẹ ẹya-aye gúsù akọkọ pẹlu diẹ ninu awọn ajakale-arun ẹya-aye àríwá (Ghana, Kenya, ati Uganda). Mẹta (12%) ni apẹrẹ ẹya-aye Gúsù (Central African Republic, Zambia, ati South Africa). Marun (20%) kò ni apẹrẹ to fojuhan (Cote D'Ivoire, DR Congo, Madagascar, Mauritius, ati Rwanda).

**Itumọ** Ọpọ awọn orilẹ-ede ní awọn àkókò ajakale-arun ayọkẹlẹ ti o ṣe é dámọ ti a le lo lati sọ fun awọn alaṣẹ ti iṣẹ arun igba aláìlásìkò ati ìgbà alásikò, itọsọna akoko ajesara, ati igbega awọn ilowosi kiakia.



**Isonigbọwọ** Ko si